# ELETI OFE

'A-NJU-WON KO ŞE WI LEJO'

VOL XIV NO 944 LAGOS SATURDAY OCTOBER 24 — OCTOBER 30 1964 KOBO MEJI (2D


ELEYI ARA!

# Awon Oyinbo Gbo'ku Odun Marundinlogoji Kan Sile Laisin

SABINA — Nkan ara ko ni tan ni orilę aiye ti a wa la lai: irohin ti oku kan ti o ku ni iwọn nkan odun m-rundinlogoji o le oşu męrin ti a gbọ lati ilu Oyinbo ti nwọn şęşę gbesin ni iję'a ni o jęki a wi bayi.

A gbọ wipe iku ara papa ni ọkunrin na ku nibiti nwọn gbe ti awọn ọlọ pa ti ri onu rę nibi ọgba ajara k n lọjọ na lọhun. Awọn Ọlọpa ni enia-dunu ni ọ unrin na, nşe ni o fark ti ọgba na bi eni ti o nsinmi nibę, ti o si ku bamubamu.

Nwọn ni nigbati dokita yę oku na wo, o ri wipe iku ọwọ Ọlọrun ni kişę wipe awọn lu u pa, şugbọn nwọn ko ri enia kan ti o mọ orukọ enii o ku na.

Boya nwọn le ri awọn enia reni Ijọba ilu Sabina ti oku na gbe ku si ba ni ki nwọn fi oogun madibaję pa a lara, awọn gbe oku na sinu posi oni jiugi kan, nwọn si lę gbe ę si gbọngan kan ki awọn ara ilu ati awọn alejo ti nwọn nwọ iiu na le ma wo o koya nipa şişe bę nwọn le ri awọn ebi rę.

Lati iwọn nkan bi ọdun marundinlogji ni oku na ti wa nibę ti ko baję rara, o dabi eni wipe o sun lọ ni., gbogbo ogunlọgọ awọn enia agbaiye ni nwọn ti wa wo oku na nib,ti nwọn gbe tę ę si fun ọdun marundinlogoji ki nwọn to lọ sin in si itę-oku ni ijęta lairi enikan ti o sọ wipe on mọ orukọ en ti o ku na,

## Olufemi Bu Eran Ogoji 'Ponun Lara Olopa Oyinbo

LCND N — Ọmọ Ilę Nigeria kan ti o nję Jọsua Akin Olufemi ni a gbọ wipe o fi ponun mọkanlelogoji ta ran si kotu kotu awọn ọlọpa ilu Oyinbo fun iijaję t o ja ọlọpa Oyinbo kan ti orukọ rę nję J hn Williams ję.

(Wo oju ewe kefa)

# Omo Olomo Ko Se Gba Se Omo

Itan yi kọ gbogbo enia Okunrin Obinrin ni ọpọlọpọ ọgbọn ati lakaye fun igbesi aiye onikaluku wa. Yio wun mi pupọ ki awọn ọkawe Eleti-Ọfę fi ara balę lati gbadun itan yi nitori ęhin ọla.

Nigba lailai ni iha ilu Shaki, orişirişi awọn alagbara ni mbę papa julọ ninu awọn ojoye ilu, ti enikan ba nfę Oye ti ko ba ni agbara, bo tilęjępe on ni Oye na tọ si alagbara yio gba ni ọwọ rę.

Oloye kan mbę ni ilu yi ni asiko na, o ję alagbara pupọ, arewa enia ni, o ni fari şugbọn ko ni igberaga rara. O ni iyawo arewa kan ti Ọlọrun ko ti fun ni ọmọ rara, awọn ọmọ ebi rę lowa ni ọdọrę.

Oloye na ko dakę on şe orişirişi ojo fun obinrin rę yi ki Ọlọrun kio le mu ọmọ wa şugbọn pabo ni o njaşi osi ję nkan ibanuj fun Ọgbęni Oloye yi: nitoripe okiki ewa rę fọnka ilu ati oko papa julọ, bgogbo ọjọ ti Ọba ba pe ipade ilu gbo gbo-gbo, Oloye yi ni on sa ba ma de ęhin ti gbogbo ilu yio si pa atę fun. Şugbọn aiko bi ọmọ kankan ti a o ma fi ọla na wo j on edun ọkan rę.

Gbogbo onka iwe yi Ọlọrun ję ki agan olukuku wa ti ọwọ bọ osun ki o fi para, ki Ọlọrun fun eniti o ti bi ọmọ ni abiye ati abiyanju ọmọ okunrin ati obinrin: Bayi ni Oloye na pęlu iyawo rę wa fun ọdun gbọrọ. ọkan ninu ohun ọşọ oloye yi ję oşu ti bi anso męt ti o da si ori rę,

Ko yi tan o o ma ba iyoku ni ọsę miran, ma şe ra iwe ni iwọ nikan ra fun ọmọ rę, ọrę rę ati iyawo nitoripe o n ri kọgbọn ni itan na ję.

# ELETI - OFE

(A NJU WON KO SE WI LEJO)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI OFE" Lagos
P. O. Box 467, Phone 23370

VOL. XIV NO 944 SATURDAY Oct 24 — Oct. 30 1964.

# Dokita Allen Lo Si Ewon Osu Meji

EKO — Onidajọ ni kotu Ọlọpa ni ijẹrin. ju Dokita Allen ẹn ti a fi ẹsun rẹ si iwaju onidajọ pe o lo iwe irin ajo alaparutu a ti pe o fẹ sakoro ninu ile Nigeria ni asiko ti ijọba mba ṣe ẹjọ.

Dokita Allen ẹniti o yi orukọ rẹ pada si Alhaji Manu Hassan Dogo sọ fun Adajọ pe on ko ni nkan kan lati sọ. Adajọ ni ṣe ẹwọn ọṣu mẹrin oṣu meji meji lori ẹsun konkan ti a so mọ lẹsẹ, ki ẹwọn na si jẹ alaṣẹ pọ. Eyi ni wipe oṣu meji pere ni pio gbe lọgba ẹwọn.

# Onisegun Kan Gbiyanju Lati Ji Oku Gbe

AWKA : Awọn Ọlọpa Ọtẹlẹmuyẹ nru igberiko ti inu ilu Awka lati wa Onisegun kan ti o lọ si isa oku ni Awka ti o si hu oku kan jade.

Ngbati o isegun si ngbe oku na lọ, o pade awọn enia diẹ ni ọna, o ju oku na silẹ o si sa wọ inu igbo lọ..

Awọn enia wọnyi sure lọ so fun awọn Ọlọpa, sugbọn ki awọn Ọlọpa na to de bẹ, onisegun na yi ti ba inu igbo lọ. Awọn ọlọpa wa titi wọn ko ti ri, wọn gbe oku na pada lọ si iru isa rẹ, nwọn tun sin.

Lowọlọwọ yi awọn ọlọpa si nwa Onisegun na kiri.

# Aja Olopa Ba Awon Olosa Ja

EKO — Ọrọ ti di orin to ti ko ja tana fun awọn Ọlọsa ti nwọn nmu mọto wa kẹru l'Eko loru ọganjọ nitorire bi awọn aja ọlọpa ti nwọn nṣọ ode nisisiyi ti muna to bẹni awọn ọlọpa ti nwọn nmu wọn kiri paapa muna. Iru nkan bẹ ni o ṣẹlẹ loru ọganja larin awọn ọlọpa ati awọn ọlọṣa ti nwọn gbe mọto wa fọ ṣọbu ni Ita Akanni

Gbara ti nwọn ti gunlẹ pẹlu mọto akẹru wọn na ni awọn ọlọpa asọde ti fojukan wọn sugbọn awọn ọlọsa na ko jafara rara nse ni awọn na ba tun ko si moto wọn pada ti nwọn fẹṣẹfẹ.

ju efin oloro si wọn.

Ngbati awọn olosa yi ri wipe awọn Ọlọpa yi ko pada lẹhin awọn ni nwọn ba bẹrẹsi yinbọn si mọto wọn.

Moto isọde awọn ọlọpa na pelu aja wọn ti nwon npe orukọ rẹ ni YOGI paapa gbatẹle wọn Moto bọlugi oni namba LG 71-25 ni awọn ọlọṣa na gbe wa jale

Awọn ọlọpa ti nwọn ọlọpa ti nwọn nsọde na bẹrẹs le wọn titi nigbati awọn ọlosa yi ri wipe nwọn ko pada lẹhin awọn ni nwọn ba bẹrẹsi ju igo lu mọto awọn ọlọpa na; nwọn fọ jingin mọto na. Eleyi ni o mu awọn ọlọpa

Nwọn le wọn titi lọ si Ọlọrunsogo nwọn ya gba ọna Isaga titi de Isọlọ Ni Isọlọ ni nwọn ju moto wọn sile ti nwọn ba sasinu gbo nibẹ ni aja ọlọpa paapa ba bẹ sinu igbo pẹlu wọn ti o wọ iya ija pẹlu ọkan ninu wọn ti o si jaje patipati.

Awọn ọlọpa ti mu ọkan ninu awọn ọlọsa na ti nwọn ri mu wa si itimọle nwọn si nwa awọn yoku kiri nisiyi;

# Oxfam Removes Snake Threat

LONDON — The orphan children at Saint Therese's Convent, Use Abat, will soon be housed in a new building which will have a snake and insect-proof floor, thanks to further aid from the Oxford Committee for famine Relief.

Of the latest Oxfam grant of £1,170 for rebuilding the orphanage, £480 is to be spent on providing a new floor for the orphanage which it is hoped will prove successful in keeping out insects and snakes which have been able to bore their way through the present floor.

# Eleti-Ofe Daraba

# Bisobu Agba Gbadura Fun Awon Oniwe Irohin

EKO — Ninu isin akonṣe fun iranti ọjọ Luku tị nwọn ṣe ni ijeie ninu Ṣọsi Alagogo ti Ẹhingbẹtı, Ẹnị-ọ w ọ bısọbu S. I. Kale gbà adura fun gbogbo awọn akọwe oniwe irohın tı nwọn mbẹ ni ilẹ yı patapata. O nị ki Oluwa Olodumare ninu anu rẹ kı o ran wọn lọwọ kị nwọn le ma ṣe iṣẹ wọn nị ọna ti o tọ atị ọna ti o yẹ

Bisọbu Kale n i k o si woli ti a le fi ịṣẹ a w ọ n oniwẹ ırohın we ju wolị Luku lọ nitorịpe o n nı ṣe ịrohın nịgbati Jese Kirisititi wa laịye fun wa nị nu Bibeli lelole o.

Aleịo Oyinbo ọmọwe kan Dokita Stephen Neil ti Unifasiti ilı Hamburg ni Jamanị ni o ṣe iwasu lọjọ n a o s sọ wabiwosị ọrọ lori ịṣẹ ribiribi ti Woịị Luku ṣe laiye gẹgẹbị dokita ọniṣgun atị akọwe ihinrere Dokita Neil ni iṣe pat ki nị iṣẹ awọn oniwe irohin o si yẹ l ị nwọn l a se e pẹlu suru ati nị ọna otịtọ.

Ninu awọn enia pataki tị o wa sị ibi isin akanṣe na nị Oloye T. O. Bensan, minịsịta alamọjuto ikede Ijọba Apapọṣe pẹ aya rẹ. Oloye Benson i o ka okan ninu awọn ẹ k ọ i wẹ inu Bịbeli ti nwọn ka lọjọ na.

Dokita I. O. Thomas ti ịlewegiga nibiti nwọn ti nkọ awọn dokịta l ẹ k ọ l'Eko nị o ka ẹkọ kejị Ọ ọlọpọ awọn onịsegun nị nwọn pe ıbẹ.

# Popu Aguda So Awon Enia Dudu Di Woli

ROME — Popu Olorị awọn Padị Ijọ Aguda tị s awọn enia dudu mejịlelogun ilı Uganda dı Woli-m mọ ninu isin nla kan t awọn ṣe nu Ṣọṣi St Pete Basıbia fu ıku ajẹriku tı nwọ ku nigbatị awọn a ılu kan pa wọn ni ịpa oro larin ọdun meji si ra wọn.

Gẹgẹbi irohın ti a gbọ nịpa ıku a w ọ n ajẹrịku na, Ọba ilu Uganda kan ti nwọn npe orukọ rẹ nị Mwanda n i o p ṣẹ wipe ki nwọn pa awọn ajerıku na nigbati nwọn ko i s i n awọn Aguda wọ ilu wọn ninu ọdun 1885.

Awọn opịtan ni awọn ajẹriku Aguda yi nikan kọ ni Ọba na paṣẹ wipe ki nwọn pa n w ọ n tun p a awọn ajẹriku Ij Ṣọṣị awọ Angilıkan pẹlu.

A gbọ wịpe P pu p ap npalẹmọ latı rị irin a ara I n d ị a On lọ sı i awọn ai yıo aị jẹ Po kinni ti yıo lọ si ırin ajo tị o jinna. Awọn ara ilu India na paapsi ti palẹmọ lati ṣe aṣeyẹ nla fun P pu na.

# Gbese Kosi, Esin Kosi

EKO— Gbese kosi. Ẹsin ko si Jugbọn ni ijẹfa ni Adajọ-agba kotu ganran kan, Ọgbẹni J I C Taylor paṣẹ wipe ki hwọn minista alamọjuto iṣẹ ijọba Apapọṣe, Alhaji Inua Wada ati Mallam Musa Gashaṣi ti nwọn ro mọto akẹru lawan lọdọ awọn Oyinbo kan ti orukọ ile iṣẹ wọn njẹ Nigerian Technical Compans, lọ san owo wọn fun wọn.

Awọn Oyinbo na ni gbogbo owo ti awon minisita mejeji na jẹ awọn jẹ £33,868: 13 .6d lori awọn moto akero ti nwọn wa ra lọwọ awọn ti nwọn ni awọn a ma san owo na diẹdiẹ lati nkau bi ọdun mẹfa.

Adajọ Taylor ti o da ẹjọ na ni o yı on lẹnu pupọ lati ri wipe lati bi ọdun mẹta ti awọn Oyinbo yi ti pe awọn minisifa ọmọ ẹgbẹ Olomi yi lẹjọ ko si ọkan ninu awọn mejeji ti o fi igbakan wa si kotu lati wa jẹ ẹjọ nẹ.

Awọn minisita mejeji gba wipe nitotọ ni awọn jẹ awọn Oyinbo onimọto na lowo ṣugbọn kọ lati san owo-ele ti nwọn sọ wipe o ti gun ori owo na.

Adajọ kotu ganran ni on mbọ wa lati so ni irinẹṣẹ ti nwọn ni lati san fun awọn Oyinbo na laipẹ yı fun wọn.

## Egbe UPGA Jade Lati Ba Ominira Wa Je :- S. L. A

Olotu Iwọ-Orun ẹniti nṣe aṣịwaju fun ẹgbẹ Demo sọ ninu ịpade kan ti o ṣe nı ọjọ kejịdịnlogo oṣu yi ninu ilu Ogbomọṣọ, ti ıpade na si kun fun ogunlọgọ enia ti wọn w ṣe ıpade yı lati orırori ilu bı mẹtalelọgọrin, awọn wọnyi jẹ aṣoju N P C ti Iwọ Orun Nigeria.

( Wo yoku loju ewe karun )

# Owo Olopa Te Alhaji Allen Ni Idi Iroko

IDIROKO— Olori akẹkọ kan nipa eto aje ti ile ẹkọ giga ni ilu (Leeds) ti ilu Oyinbo, ti Ijọba apapọṣe mba ṣe ẹjọ nipa ẹsun pe o fẹ doju Ijọba apapọ delẹ ni a gbọ wipe o gbidanwo lati salọ ṣugbọn ọwọ awọn ọlọpa tẹ ni Idi Iroko ni oru ọganjọ.

Dokita Victor Leouard Allen ni a gbọ wipe o fi nkan kun ara rẹ ni oju ati ọwọ ki o le jọ enia dudu. O si tun mura gẹgẹ bi awọn Hausa o we lawani baba tutu o si mu tẹsba dani gẹgẹbi Imale. O wọ mọto takisi lati sọda kuro ninu ilẹ Nigeria ki o le salọ.

Ngbati o de Idi Iroko, pẹlu ọmọ ilẹ Nigeria kan, nibiti a o yẹ iwe ẹri ikọja rẹ wo, o yi oruko na pada si Alhaji HASSAN DOGA O ni ọmọ Hausa Kano ni on nṣe. Nigbati awọn Ọlọpa fura si i ti nwọn si da duro, ọmọ Nigeria ti o ṣe ekeji rẹ fi ẹsẹ fẹ, o fi papa bora.

Ni ọsẹ ti o kọja ni Adajọ Kotu awọn Ọlọpa ti Ikẹja sọ wipe on yio da ẹjọ wọn ni ọjọ kẹwa oṣu ti mbọ. Adajọ na gba Iduro fun on pẹlu awọn meji ti wọn ba ṣe ẹjọ idoju ijọba Apapọ delẹ, Agbejọro wọn bẹbẹ pe ki adajọ sun irin ẹsẹ wọn si dede Ilu Jos. Ṣugbọn Adajọ na kọ, o ni wọn ko gbọdọ kọja kọja igba ibusọ si Eko.

# Eto Oba Eko Yi Si Maganna

EKO— Ni ọjọ ọsẹ ni ọjọ kejidinlogun oṣu yi ni a gbọ wipe nwọn yan oloye Saba lati rọ ipo Ologbe Ashogbọn ẹniti ti o di Ologbe ni nwọn oṣu diẹ sẹhin ti nwọn ko si ti yan ẹnikan si ipo na na lati ji roro ẹniti nwọn yio mu gẹgẹbi Ọba ilu Eko. Oye Ashogbọn jẹ ọkan pataki ninu awọn afọbajẹ.

Nigbati awọn ẹbi Oloye Ashogbọn gbọ eto yi, nwọn fọnnun pe awọn ko le gba ki oloye Saba ba awọn ṣe nkan idile awọn rara nwọn fi han awọn Afọbaje wipe awọn ti yan Ọgbẹni Olu Akapo ko si si isina nibẹ ti ẹniti ẹbi yan na ba joko pẹlu awọn afọbajẹ lati jiroro nipa yiyan Ọba omiran fun ilu Eko ti nwọn fẹ yan laipẹ yi.

A ri gbọ wipe awọn ọmọ Eshilokun ranrin pe idile awọn ni ọba kan, nitoripe idile na ti jẹ ọba gbẹhin lati ọdun 1780, nigbati ọba Adele kinni wọ Aja.

Ọmọ ọba Adeyinka Oyekan ni on ko fẹ ki awọn afọbajẹ ko iyan on kere nitoripe idile ti awọn ni ni Oye Ọba Eko kan, on si ni gbagbọ awọn ọmọlẹbi on yan sode fun oye na.

---

## E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin Eleti — Ofe ti o kun fun irohin aladun losose.

E ka oro Popu Agụda So nipa awọn Enia dudu Woli (Wo oju ewe keta)

# Olotu Ijoba Iwo orun Ki Olotu Ijoba Ilu Oyinbo

IBADAN — Oloye S. L. Akintọla ti nṣe Olotu Ijọba Ilẹ Iwo orun ni ilu Nigeria fi kiki ranṣẹ si Olotu Ijọba Ilu Oyinbo Ọgbẹni Harold Wilson ẹniti nṣe aṣiwaju fun Ẹgbẹ oṣiṣẹ ti awọn ọjọ rẹ bori ninu ibo ti nwọn di kọja ninu ọsẹ ti o lọ.

Oloye Akintọla ki bayi pe :-

Gbogbo ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) ti mbẹ ni Nigeria yọ gidigidi fun ibori awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ninu ibo ti nwọn di kọja na. Awa ni ireti pe isowọpọ pẹlu awọn enia ilu Afrika ki yio ja, awọn ti o ṣe pe ẹgbẹ rẹ ja fun gidigidi lati yẹ kuro ninu ajaga, ti a [illegible] fun ni Ominira.

# NATIONAL BANK OF NIGERIA LIMITED



**Incorporated in Nigeria in 1933**

**Paid up Capital – £3,181,000**

## HEAD OFFICE:

82/86, Broad Street, Lagos, Nigeria
Telephone 20511
Cables & Telegrams NATIONBANK LAGOS

## LONDON OFFICE:

15, THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Telephone LONDONWALL 4303
Cables & Telegrams NATBANIGER LONDON.

## 30 BRANCHES IN NIGERIA

CORRESPONDENTS IN ALL PARTS OF THE WORLD

EVERY DESCRIPTION OF BANKING BUSINESS TRANSACTED.


## Egbe UPGA Jade Lati Ba Ominira Wa Je SLA

( O bẹrẹ loju ewe kẹta )

N ou ọrọ rẹ Oloye Akintola sọ fun wọn enı-nwọnyi wipe, ni wọn ọdua dẹ sẹhin nį a ti g iyacjn Ipasẹ Iun en a kan ṣoşu ki o w fun o i e ede kao k n ti o ba gh Omnira sugbọn ko şeşe rara iba kib nibiti a si gb rį iri-rẹ ışe nį c p iye miu nira ẹ kọk n de mọ wọ-lara, depo t o jẹ wipa ẹ kẹn ko nį om, rae ar rẹ mọ ni u ,le t bį lar u nu.

Oloye Akintọla fi h n ọ ti wa si ipade a n y e, u ofin y ni egbẹ Ọlọpẹ ati ẹgbẹ Alakuko fe şe fun v a ni Nigeria. Lati g e ofin e ọ v o eo kan şoş rį ko į s e tį yio yẹ ofin yi wo ab ti yio yi pada.

Oun fi han ipade yi pe ko tį ju okan bi ọdun m rin ıọ ti a bọ nį oko ẹrusin awọn ijọba ges, o ha to ki a u bọ si oko rus o arawa bį, nitor, eyi fi han dajud ju pe egbẹ Alakuko ati Ọlọpẹ fi ti wa s oko ẹru nį;

Olotu ijọba Iwọ orun fi ye wọn wipe Ilu adehun ipolowo ibo tį awọn apa-pọ ẹgbẹ Alakuko ati Ọlọ-pẹ şe wipe awọn yio fun olori Ilu Nigeria (President ni agbara ju bį o tį wa yi lọ jẹ iwa gẹgẹ bį tį Hitler tį Ilu Germany ta bi Mu-solini ti Ilu Italy.

Nitori iwa agbaraebe awọn yi ẹ ko gbọdọ di ibo yin fun wọn.

# Oba Olofa Pada S'ofa Lati Ihamo

ỌFFA — Gbogbo awọn ara Offa nį nwọn fi tayọ tayọ gba Ọba Wuraola Isioye Ọlọfa ana ti Ijọba Oke Oya fi įgbakan wa kuro lu lọ si Ogbomosho nitorį ede aiyede ọrọ ilu ki nwọn to fi elomįran je dipo re.

Ni aipeyi ni Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello, Sardauna Sokoto se abewo lọ si ilu Ilorin pẹlu Offa ti o si se ileri nbi eyẹ kan ti nwọn se fun wį, c on a sa agbara atį ri wipe Ijọba awọn da Ọba Ọlọfa ana pada si įlu rẹ kį oṣu yi to pari.

Ngbati awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan gbọ ọrọ na nwọn ni nįtori ki awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu Sardauna Sokoto ba le moke lori idibo gbogbo tį nwọn fẹ dį yį nį o jẹki o ṣe ileri bẹ.

A gbọ wįpe inu Ọba Olọfa paapa dun lati tun fẹse kan ilu rẹ lati nkan bi ọdun mẹfa ti nwọn ti wa lọ si Ogbooshọ.

# Odara Kan Sun Asungbagbe Lo Sewon L'Eko

EKO — Okunrįn kan ẹni ọdun mẹdọgbọn to nṣe ṣẹ oni ẹlẹntrįki ni a gbọ wipe o pįdan h n adajọ kotu awọn ọlọpa kekere kan ni Eko ninu oṣu yi nigbati o ṣe gẹgẹbi o ti ṣe ni on gbagbe sunlọ nį opopo leti ebute Ẹhingbẹti ni oru ọjọ ti awọn ọlọpa mu on ọlọpa to mu ri nṣe ni o ajẹgboro kikiri nįtosi ẹnu ọna to wọ ọgba ile Bilẹ ijọba Apapọṣe ti o nwa ọna ti yio gba wọ ile na lati lọ ko wọn ẹru nibẹ ki on to taju kan rįn.

Nigbati ọlọṣa na ti orukọ rẹ nję Rasidį Ọlade e de kotu, o nį ibį ajọyọ ikomọjade kan nibitį on gbe ti mu ọti yo ni on ti mbọ ki on to gbagbe sunlọ sį ebute Ẹhingbẹtį nigbati on duro de ọkọ ti yio gbe on sọda si įbikan ti nwọn npe ni abule ogogoro ti o gbe ngbe.

Ọdaran na nį ọtį ti awọn mu ibi ikomọjade na pọ lọjọ na to bẹ gẹ tį o fi rẹ on ti o on ni lati gbagbe sunlọ sori ijoko. O nį asungbagbe ni o ṣ en, on ko fẹ jale rara l'Ẹhingbẹti.

Ṣugbọn gbogbo aroye rẹ nį adajọ sọ pe ko waiye rara niwaju on ka wi ka fọ nṣe ni o ba sọ sẹwọn oṣu m san pẹlu iṣẹ aṣelara.

Alaye ti awọn ọlọpa ṣe nį wipe, awọn mu Ọlọde'e nibiti o gbe npọn ogiri ẹnu ọna ti apa iha iwọ orun ti ile Bilẹ ijọba Apapọṣe ni ọjọ kẹwa oṣu yi, ṣugbọn ọdara na sa mọ ọlọpa to mu lọwọ, ko pẹ lẹhįn na ni ọwọ tuu lẹ, nwọn mu lọ sį ọgba awọn ọlọpa.

# Olopa Dongari Ko Awon Omo Egbe N E P U

KONTAGORA — A gbọ wįpe awọn mẹdogun ti nwọn jẹ enia patakį ninu awọn ọmọ ẹgbẹ NPU nį awọn ọlọpa dongarį ko lọ ti mọle na se, nįpa ọrọ įdibo.

Gẹgẹbį alaye tį ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu NEPU ti nwọn ko t mọ e na ṣe o nį lọjọ ti nwọn wa ko awọn, ninu ile kan awọn aṣiwaju ẹgbẹ awọn ni awọn se ipade O ri awọn ko ṣe ipade įwọde rara.

A gbọ wipe Alhaji Aminu Kano tiṣe baba ẹgbẹ wọn wa ninu awọn Olorį wọn ti o ba nwọn sọrọ ninu ipade abẹ ile ti nwọn se ni alẹ ọjọ na. Nwọn nį gbara tį Alhaji Aminu Kano ti kuro įbẹ ni awọn ọlọpa Dongari ti gba wọn mu, ti nwọn si lọ ti nwọn mọle.

Nwọn ko ti gba iduro enikan ninu wọn di bį a ti nkọ irohin yį lọwọ. Awọn enia awọn ara ilu ti nwọn ko timọle ni nitorį ọmọ ọba ilu na tį awọn ẹgbẹ Olomi (N P C) gbe jade wipe kį nwọn dibo fun nį o jekį nwọn ma nį awọn ara ilu lara ki nwọn ba le dibo fun ọmọ ọba na tipa tipa.

A tilẹ tun gbọ irohįn wipe pelu ofa ati atori bilala ni awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi (N P C) nkọ lọ fi ṣe ipolowo įdibo nį Oke Ọya.

# Olufemi Bu Eran Ogoji Ponun Lara Olupa Oyinbo

Nigbati ọlọpa Williams tį nwọn fajẹ na ẹsọrọ ni iwaju adajọ o nį ọdaran Olufẹmi na n o wa rojo fun awọn ni itẹsan awọn wįpe Oyinbo aladugbo on kan oyinbọn si on lati oju ferese nibiti on gbe ti nse onjẹ.

Ọlọpa yi ni nįgbati awọn ba a de ile na Ọgbeni kan ti nwọn npe ni Draper ni awọn ri Ọgbenį na ni kosį ẹnį ti o ni ibọn ipẹyẹ ninu ile awọn rara.

O ni nigbati awọn so fun ọdaran yi wipe kį o lọ pẹ jọ ti o ba ri wipe nitotọ ni owọn n y i n b ọ n sį on Ọlọpa na ni esi ọrọ yi ko dun mọ ọdaran na ninu rara, nṣe ni o beresį bu awọn kasakasa tį o sį bu on jẹ lapa.

Olufẹmi ni on ko deede ṣe bẹ nṣe ni awọn ọlọpa na lo on lapa sẹhįn ti nwọn lẹ ṣe on leṣe.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28,Kosoko Street
Phone 23370 Editor, (Olotu) Ola Onatade 15,Kosoko Street, Lagos, P O 467 Lagos.